# IKẸYIN ỌJỌ́

## 1 Timoteu 4:1-9; 2 Timoteu 3:1-7

## ẸKỌ 414 --- FUN AGBA

**AKỌSORI: "Ṣugbọn Ẹmi ntẹnumọ ọ pe, ni ìgba ikẹhin awọn miran yio kuro ninu igbagbọ́, nwọn o mã fiyesi awọn ẹmi ti ntan-ni-jẹ, ati ẹkọ́ awọn ẹmi èṣu" (1 Timoteu 4:1).**

**I Kikuro Ninu Igbagbọ́**

1 Ẹmi n kilọ pe awọn miiran yoo lọ kuro ninu igbagbọ́, 1 Timoteu 4:1; 1 Johannu 2:18, 19

2 Awọn ti n kuro ninu igbagbọ́ a maa fi ẹ̀kọ́ ẹmi eṣu ati agabagebe awọn ti nṣeke dipo otitọ, 1 Timoteu 4:1, 2; 2 Timoteu 4:3, 4

3 Wọn n fi agbara mu ni lati pa ofin eniyan mọ́ dipo ofin Ọlọrun, 1 Timoteu 4:3-5; Marku 7:6-8

**II Ojuṣe Awọn Ojiṣẹ Ọlọrun**

1 Ojuṣe awọn ojiṣẹ Ọlọrun ni lati maa fi ọ̀rọ igbagbọ́ ati ẹ̀kọ́ rere bọ́ awọn ara, 1 Timoteu 4:6

2 A fi dandan lé iwa-bi-Ọlọrun, 1 Timoteu 4:7-9; Titu 2:12

**III Igba Ewu**

1 Gbogbo oniruuru iwa ibi jẹ àmi ikẹyin ọjọ, 2 Timoteu 3:1-4; Matteu 24:37-39; Gẹnẹsisi 6:5-7

2 Wọ́n ní afarawe iwa-bi-Ọlọrun ṣugbọn wọn sẹ́ agbara rẹ̀, 2 Timoteu 3:5-7

ALAYE

"Ṣugbọn Ẹmi ntẹnumọ ọ pe ni igba ikẹhin awọn miran yio kuro ninu igbagbọ́, nwọn o mã fiyesi awọn ẹmi ti ntan-ni-jẹ, ati ẹkọ́ awọn ẹmi èṣu; nipa agabagebe awọn ti nṣeke, awọn ti ọkàn awọn tikarawọn dabi eyiti a fi irin gbigbona jó." Ọkan ninu awọn àmi pataki ti Apọsteli naa wi pe yoo farahàn ni ikẹyin ọjọ ni lilọ kuro ninu igbagbọ́: ipẹyindà, kíkọ ọna ìgbaani. Akoko Laodekia ni igba ikẹyin Ijọ Ọlọrun lori ilẹ-ayé, o si jẹ́ igba kò-gbona-kò-tutù, eyi ti o jẹ́ irira si Ọlọrun. Ọlọrun ti wi pe, "Emi iba fẹ pe ki iwọ kuku tutù, tabi ki iwọ kuku gbóna." Ẹ jẹ ki a ṣọra ki a ma baa di onilọwọwọ nipa ti ẹmi ni igba ikẹyin yii.

O ṣe anfaani lati ronu le ohun ti Ẹmi n sọ fun awọn Ijọ nipa Ọrọ Rẹ̀. Ọrọ Ọlọrun ni ìmisi Ẹmi Ọlọrun. Eredi rẹ̀ ni eyi ti Ọrọ naa fi yè. O yè, o si lagbara, o si n gun ni a ni titi dé pinpin ọkàn ati ẹmi niya, ati orike, ati ọ̀rá inu egungun – ti ẹmi ati ti ara.

**Ọkàn Aikú**

A dá eniyan ni aworan ati iri Ọlọrun. Nigba ti Ọlọrun mi ẹ̀mi iye si eniyan, eniyan si di **alaaye ọkàn**. O di alaaye ni ẹmi ati ni ara. Awọn ẹranko, ẹyẹ, ẹja ati awọn ohun miiran ni a dá yatọ si eniyan. Ọlọrun dá eniyan yatọ, ẹda ti o ni **ọkàn aiku** ni. O ti logo to! Ṣugbọn wo bi eniyan ti tabuku si anfaani ti a fun un lati sin Ọlorun ati lati jẹ́ oloootọ si I.

Ẹmi itanjẹ ati ẹ̀kọ́ èṣu le yọ wọ inu eniyan lọna arekereke lati ṣiṣe ẹtan ati lati mú oluwarẹ̀ kuro loju ọna tobẹẹ ti yoo fi padanu iye ainipẹkun ti Ọlọrun ti pese silẹ fun un. Nipa bayii oluwarẹ̀ yoo di ẹru eṣu - apẹyindà kuro ninu igbagbọ́ - ati ẹni ti Ọlọrun kọ̀. Ọlọrun ti wi pe awọn ẹmi ẹtan yii yoo tilẹ tan awọn ayanfẹ paapaa jẹ bi o ba ṣe e ṣe. Ẹ jẹ ki a ronu gidigidi lori nnkan wọnyii.

**Igi Itọkasọna**

Ninu Ọrọ Ọlọrun a ka bayii pe: "Eyi ni ki o mọ̀, pe ni ikẹhin ọjọ igbà ewu yio de. Nitori awọn enia yio jẹ olufẹ ti ara wọn, olufẹ owo, afunnu, agberaga, asọ̀rọbuburu." Olufẹ ti ara wọn! Ki i ṣe olufẹ Ọlọrun, ki i ṣe ofufẹ ọmọnikeji wọn, ki i ṣe olufẹ ẹwà ti igbala nla Ọlọrun, ṣugbọn olufẹ ti ara wọn! Wò yika ayé gbogbo lode oni, ki ni iwọ ri? Imuṣẹ awọn ohun wọnni ni perepere gẹgẹ bi Iwe Mimọ́ ti wi. Awọn eniyan kọ ni itẹlọrun mọ́, wọn jẹ́ olufẹ ti ara wọn, olojukokoro ati afunnu.

Ayé ifunnu ni eyi ti a wà lode oni. Awọn eniyan n funnu nipa imọ ori, ati imurasilẹ ti wọn n ṣe fun irin-ajo lọ si ofurufu ati iwadii awọn irawọ ti o jinna rére ninu awọsanma. Iba ohun diẹ ni awọn eniyan kò le fi ọgbọ́n wọn mọ̀ lọjọ oni, ṣugbọn ni iṣẹju kan Ọlọrun le da gbogbo ọgbọ́n eniyan rú gẹgẹ bi O ti ṣe si awọn olukọ ile iṣọ Babeli.

Apọsteli nì wi pe: "Ọlọ́gbọn na ha da? akọwe na ha da? ojiyan aiye yi na ha da? Ọlorun kò ha ti sọ ọgbọ́n aiye yi di wère?" (1 Kọrinti 1:20). Lẹyin ti ọgbọ́n eniyan ba ti di ilẹ, ọgbọ́n Ọlọrun yoo maa ga si i titi lọ si ayeraye.

**Awọn Eniyan Buburu**

Ọrọ Ọlọrun ṣe apejuwe awọn eniyan ikẹyin ọjọ bayii: "Afunnu, agberaga, asọ̀rọbuburu, aṣaigbọran si õbi, alai lọpẹ, alaimọ́, alainifẹ, alaile-dariji-ni, abanijẹ́, alaile-kó-ra-wọnnijanu, onroro, alainifẹ-ohun-rere." Kò ti i si akoko kan lati igba ti ayé ti wà ti awọn ọ̀rọ Bibeli ti i ṣẹ ni perepere ni igbesi-ayé awọn eniyan buburu bi ti akoko igba ti a wà yii.

Iwakiwa ti awọn eniyan n hù lọjọ oni ti peleke. Wọn kò tun fi ọwọ danindanin mu iwa rere mọ́; n ṣe ni ohun gbogbo n buru si i. Ranti, Bibeli wi bayii pe nikẹyin ọjọ "igba ewu" yoo de. Igba ikẹyin ni a wà yii. Igba ewu naa ni yii! Awọn eniyan di "alaile-kó-ra-wọn-nijanu," "alainifẹ-ohun-rere." Njẹ igba kan wà ti ayé ti i fi ara wọn fun ifẹkufẹ ara ati irera ayé bi ti ayé ode-oni?

Bi ẹnikan ba ni iwa ti o bojumu ninu ọkàn rẹ, ẹni naa yoo di ẹni ẹ̀gan loju awọn ẹlẹgbẹ rẹ. Pupọ eniyan ni o n tẹle ọgọrọ eniyan lati ṣe ibi, nitori pe eyi ni awọn eniyan ni inu-didun si. Ṣugbọn eyi le mu ki oluwarẹ̀ sọ ẹmi rẹ nù titi ayeraye sinu ọrun apaadi nipa titẹle ọpọ eniyan lati ṣe ibi. Ọlọrun korira rẹ̀!

**Olufẹ Faaji**

Bibeli sọ fun wa ju bẹẹ lọ nipa awọn eniyan ti ikẹyin ọjọ: Wọn yoo jẹ "Onikupani, alagidi, ọlọkàn giga, olufẹ fãji jù olufẹ Ọlọrun lọ." Ta ni ọrọ yii n bawi? Ẹnikẹni ti o ba ni inu-didun si faaji ayé yii ju ifẹ Ọlọrun ati Ofin Rẹ̀. Kò jamọ nnkan, yala oluwarẹ̀ wà ninu agbo ẹsin tabi kò si. Kò di igba ti eniyan ba di ẹni ti o sọ pe Ọlọrun kò si tabi alaigbagbọ́ ki o to mu Ẹmi Ọlọrun binu ki o si fa ibinu Rẹ̀. Bi oluwarẹ̀ naa ba ti le ni ifẹ ti o ga jù fun faaji ju eyi ti o ni si Ọlọrun lọ.

Nigba miiran a maa jẹ iyalẹnu fun wa bi awọn miiran ti n fi ainaani du Ọlọrun ni isin tootọ, ironu ti o jinlẹ ati iṣẹ isin wọn fun Oluwa ni titan imọlẹ Ihinrere ka; kàkà bẹẹ wọn a maa wá, wọn a si maa ṣe ohun wọnni ti o le fun wọn ni igbadun.

Ronu diẹ lori ọrọ yii: Iwọ ha i ṣe olufẹ faaji ju olufẹ Ọlọrun lọ bi? Ki ni iwọ maa n ṣe ni Ọjọ Oluwa? Ki ni iwọ n ṣe fun igbeleke iṣẹ Kristi? Njẹ iwọ n fun Ọlọrun ni akoko ati talẹnti rẹ, iwọ n fun Ọlọrun ni ohun ini rẹ ati agbara rẹ bi? Bi eyi kò ba ri bẹẹ, boya iwọ paapaa jẹ àmi ati ifarahan ikẹyin ọjọ nitori pe iwọ ni ifẹ fun faaji ju fun Ọlọrun lọ.

**Ẹsin Ode-ara**

Lẹyin ti Iwe Mimọ́ ti ṣe apejuwe awọn eniyan lọkunrin ati lobinrin ti igba ikẹyin, o fi awọn ọrọ wọnyii kun un pe "Awọn ti nwọn ni afarawe iwa-bi-Ọlọrun, ṣugbọn ti nwọn sẹ́ agbara rẹ̀: yẹra kuro lọdọ awọn wọnyi pẹlu." Farabalẹ ṣe akiyesi awọn ọ̀rọ wọnyii. Yẹ iduro rẹ ninu Ọlọrun wò kín-ni-kín-ní. Ninu Iwe Mimọ́ Ọlọrun ni awọn ọ̀rọ wọnyii ti jade wá.

Ọpọ eniyan lode oni ni wọn ni afarawe iwa-bi-Ọlọrun, ṣugbọn ti wọn ti kú ikú ti ẹmi. Wọn n tẹ siwaju ninu afarawé isin wọn, ṣugbọn kò ni agbara - wọn sẹ́ agbara Ọlọrun ti n sọni di aaye, ti n fi itara, igbagbọ́, ikiya ati igbona ọkàn fun ni fun iṣẹ Kristi.

Ifẹ wọn iṣaáju, ifẹ iṣaaju fun irapada ọkàn lọkunrin ati lobinrin wá sinu ọkàn wọn nipa gbigba idariji fun ẹ̀ṣẹ, lẹyin ti wọn ti ni ibinujẹ ẹni iwa-bi-Ọlọrun; ṣugbọn nisisiyii ẹmi eṣu ti n tannijẹ ti yọ́ wọle, o si yẹ ifẹ, itara ati igbagbọ́ ati awọn ẹ̀kọ́ ti wọn ti fẹran lẹẹkan ri lẹṣẹ. Nisisiyii wọn ti kunà wọn si wà laini Ẹmi Ọlọrun ti n sọni ji, ṣugbọn wọn n tẹsiwaju ninu afarawe nikan.

**Ṣọra**

Ẹni kọọkan ni Ọlọrun n ba lò lọkunrin ati lobinrin. Nipa Ọrọ Rẹ̀ ni O n fi Ifẹ Rẹ̀ hàn. Bi ẹnikan ba di eti si Ọrọ Rẹ̀, oluwarẹ̀ naa yoo kunà ninu isin rẹ si Ọlọrun; ifẹ rẹ̀ si Ọlorun yoo di baibai; yoo si sọ itara ti o ni fun Ijọba Ọlọrun nù. Bi eyi ba jẹ iru ipo ti o wà, o ni lati mọ pe nnkan kan sọnu ni igbesi-ayé rẹ. O si ni lati boju to o ki o to pẹ ju.

Ki Ọlọrun maṣe jẹ ki awa, bi ẹni kọọkan tabi lapapọ, ṣubu sọwọ ẹmi ilọkuro ninu igbagbọ́ eyi ti o ti de ba awọn ijọ alafẹnujẹ - awọn ti o n fi ẹnu jẹwọ ijọ Ọlọrun – ni igba ikẹyin yii. Ki Ọlọrun maṣe jẹ ki a sọ igbona ọkàn, itara ati ifẹ gbigbona lati fi gbogbo tiwa fun igbeleke ogo Kristi nù. Ki a le fi gbogbo itara wa sin In, ki a si le fun Un ni akoko wa, talẹnti wa ati agbara wa.

Otitọ ni Ọrọ Ọlọrun; nigba ti a ba kọja si ayeraye gbogbo awọn wọnnì ti kò gba a gbọ́ lọjọ oni yoo ri i daju pe otitọ ni. Nigba naa gbogbo eniyan yoo mọ̀ pe Bibeli yii jẹ Iwe Iye, Iwe Ọlọrun, Iwe ti n sọ bi ibugbe ayeraye olukuluku yoo ti ri. On ni iwe ti n fi ọ̀na Ọrun han olukuluku eniyan.

Ọlọrun ma ṣai sọ ọkàn wa ji; ki o máṣe si ohunkohun laye yii ti yoo mu ki ẹmi igba ewu ti a wà yii wọ ọkàn wa tobẹẹ ti a o fi jẹ́ alafara ati alainaani ninu iwa ati iṣe wa niwaju Ọlọrun.

**Akoko Itẹwọgba**

Lonii ni igba ti a gbọdọ ni isọji ọkàn. Lonii ni ọjọ imurasilẹ. Lonii ni ọjọ igbala. Ki ni yoo jẹ́ ipin rẹ bi Oluwa ba mu ayé yii wá sopin lonii?

Lonii ni akoko itẹwọgba lati wá idariji lọdọ Ọlọrun – akoko ti Ọlọrun yoo gbà ọ́. Ọrọ naa ni ki o gba A gbọ́. Ọlọrun yoo gba ọ ọrẹ ẹlẹṣẹ, onilọwọ́wọ́, afasẹyin, okú alafẹnujẹ ẹlẹsin, bi iwọ ba le ronupiwada.

Ọlọrun n pè. Bi iwọ ba le gbọ́ ohun Rẹ̀, maṣe sé àyà rẹ le ṣugbọn wá sile sinu ifẹ Ọlọrun – ki o si murasilẹ fun ọjọ ikẹyin nì.

**AWỌN IBEERE**

1 Ta ni kilọ fun wa pe ilọkuro ninu igbagbọ́ yoo wà lokoko ikẹyin?
2 Ki ni awọn ti o lọ kuro ninu igbagbọ́ fi dipo otitọ?
3 Ki ni o n ṣẹlẹ si ẹri-ọkàn awọn ti n lọ kuro ninu igbagbọ́?
4 Njẹ o yẹ ki a kọ ohunkohun ti Ọlọrun dá? Bawo ni o ṣe yẹ ki a gbà wọn?
5 Ki ni o yẹ ki a kọ̀?
6 Sọ ẹsẹ ọrọ yi ni kikun: "Iwa-bi-Ọlọrun li ère fun ohun gbogbo …?
7 Igba wo ni igba ewu yoo dé?
8 Sọ ami mọkàndinlogun ti o n fi igba ewu hàn gẹgẹ bi a ti sọ asọtẹlẹ rẹ̀ ninu ẹ̀kọ́ wa ti oni.